# PAULU ATI SILA NINU TUBU

### Işe Awọn Apọsteli 16:9 - 40

### ẸKỌ 334 --- FUN AWỌN ỌDỌ

**AKỌSORI: "Bi iwọ ba fi ẹnu rẹ jẹwọ Jesu li Oluwa, ti iwọ si gbagbọ́ li ọkàn rẹ pe, Ọlọrun ji i dide kuro ninu okú, a o gbà ọ là" (Romu 10:9).**

**Iranlọwọ**

"Rekọja wá si Makedonia, ki o si ran wa lọwọ"; eyi ni ọ̀rọ ti Paulu gbọ́. O ri iran ni oru. O ri ọkunrin kan ara Makedonia ti n bẹbẹ fun iranlọwọ. O n fẹ ki Paulu ran oun lọwọ lati mọ̀ nipa Jesu.

Paulu ti şe iranwọ fun ọpọlọpọ eniyan ninu irin-ajo rẹ ekinni. O ti şe iranwọ fun wọn nipa ti ẹmi. O ti waasu nipa Jesu, ọ̀pọlọpọ eniyan si gba ọ̀rọ rẹ gbọ́. Paulu ti şişẹ fun Oluwa ati fun awọn eniyan rẹ. O dá ijọ silẹ o si yan awọn alagba ninu ijọ kọọkan.

Makedonia jẹ́ ilu ti o jinna rére ni odikeji okun lọhun. Paulu yoo ha lọ si ibi ti o jinna to bayii lati lọ ran ẹnikan ti kò mọ̀ ri lọwọ? Bẹẹni, Paulu n fẹ lati tan Ihinrere kalẹ. O gbà pe iran yii jẹ́ ipe fun un lati waasu Ihinrere fun awọn ara Makedonia. Ki i şe igba gbogbo ni Ọlọrun maa n fi iran han awọn eniyan nigba ti o ba n pe wọn si işẹ ajihinrere. Nigba miiran awọn eniyan a maa kọwe lati beere fun iranlọwọ. Nigba miiran, Ọlọrun maa n fi iwuwo si ọkàn awọn eniyan Rẹ̀ nipa awọn eniyan kan ti o wa nibi kan. Nigba miiran ẹ̀wẹ, Ọlọrun le fi si wa lọkàn lati pe ẹni kan wá si Ile-ẹkọ Ọjọ Isinmi ati sibi isin. Ki i şe ilu okere nikan ni işẹ Ajihinrere pẹ̀kun si. Awọn eniyan wà ni arọwọto wa ti wọn n fẹ iranwọ. Ọlọrun le lo ọmọ-kekere pẹlu ninu işẹ Ajihinrere Rẹ̀.

**Lilọ Lọgán**

Lẹyin ti Paulu ti gbọ́ ipe lati lọ si Makedonia, o mọ̀ pe Ọlọrun n fẹ ki oun lọ si ilẹ ti o jinna réré nì. Paulu ti ni idaniloju pe Ọlọrun n fẹ ki oun lọ waasu Ihinrere fun awọn eniyan wọnyii. Eniyan lè ni idaniloju ipe ti a pe e. Eniyan le mọ ifẹ Ọlọrun pẹlu. Nigba ti eniyan bá gbadura, pẹlu ijọwọ-ara-ẹni-lọwọ lati lọ tabi lati duro, Ọlọrun yoo fi ohun ti yoo şe hàn án.

Nigba ti Paulu ti ni idaniloju ifẹ Ọlọrun, o mú Sila pẹlu rẹ̀ o si lọ si Makedonia lẹsẹ kan naa. Boya o ni irú ọkan kan naa pẹlu Dafidi, ẹni ti o wi pe, "Işẹ ọba na jẹ́ işẹ ikanju" (1 Samuẹli 21:8). Paulu n şişẹ fun Jesu, Ọba awọn ọba, o si mọ̀ pe oun ni lati şişẹ nigba ti anfaani wà lati şe bẹẹ. Awọn ẹlomiran a maa fi oni dọla lati şe ifẹ Ọlọrun. Nigba miiran wọn ni ohun kan ti wọn fẹ şe ti wọn kò si fẹ fi silẹ. Nigba miiran ẹwẹ, wọn ni nkan miiran ti wọn n fẹ şe ki wọn to wá şe ifẹ Ọlọrun. Nigba miiran wọn maa n fẹ lati ronu le e lori fun ọjọ pipẹ ki wọn to pinnu lati gbọran ati lati şe ifẹ Ọlọrun. Paulu kò ni ilepa miiran ninu igbesi-aye rẹ̀ ju pe ki o şe ifẹ Ọlọrun lọ. Paulu şetan lati gbọran. Nigba ti anfaani bá şi silẹ lati tan Ihinrere kalẹ ati lati ran awọn ẹlomiran lọwọ lati mọ̀ nipa Jesu, Paulu şetan lati lọ, o si şetan lati şişẹ.

**"Mo fẹ lọ, mo si fẹ duro,<br>Mo fẹ dipo mi mu;<br>Mo fẹ şişẹ nla tabi kekere,<br>Mo fẹ şe ifẹ Rẹ."**

**Ni Filippi**

Paulu ati Sila şikọ lati Troasi, nikẹyin wọn de Filippi, ti i şe olu ilu Makedonia. Wọn duro nibẹ fun ọjọ diẹ. Wọn şeto lati ni ipade adura leti odo kan lẹyin ilu. Awọn obinrin kan pejọ sibẹ, Paulu si bẹẹrẹ si ba wọn sọrọ.

**Onişowo Elese Aluko**

Ọkan ninu awọn obinrin ti o gbọ́ ọ̀rọ Paulu ni a n pe ni Lidia. O jẹ́ ara ilu kan ti a n pe ni Tiatira, ilu ti o ni okiki nitori işẹ aró rirẹ. Lidia n ta aró wọnyii ni Filippi. Obinrin yii jẹ ẹlẹsin o si n sin Ọlọrun.

Bi o ti n gbọ́ ọ̀rọ Paulu, o gbọ́ nipa Ọmọ Ọlọrun, ani Jesu Kristi. Oluwa bá ọkàn Lidia sọrọ. O gbagbọ ninu awọn ohun wọn ni ti Paulu sọ. O ṣi ọkàn rẹ̀ payá o si gba Ihinrere, o si di ọmọlẹyin Kristi.

**Iribọmi**

Bi eniyan ba gbadura, bi o ba mọ ara rẹ̀ ni ẹlẹṣẹ, ti o si bẹbẹ pe ki Ọlọrun dariji oun, ti o si gba Jesu Kristi Oluwa wa gbọ́, oluwarẹ yoo ri igbala. Nigba ti eniyan ba di atunbi, oun yoo fẹ ṣe iribọmi. Ifẹ Ọlọrun ni. Iribọmi jẹ́ apakan Ihinrere, Oluwa si n fẹ ki awọn eniyan Rẹ̀ gbọran si ohunkohun ti i ṣe ti Ihinrere. Nigba ti Oluwa fi Aṣẹ Nla nì fun awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀, O wi pe, "Nitorina ẹ lọ, ẹ ma kọ́ orilẹ-ède gbogbo, ki ẹ si ma baptisi wọn li orukọ Baba, ati ni ti Ọmọ, ati ni ti Ẹmi Mimọ́: ki ẹ ma kọ́ wọn lati ma kiyesi ohun gbogbo, ohunkohun ti mo ti pa li aṣẹ fun nyin" (Matteu 28:19, 20).

Ninu Bibeli, ni a ri apẹẹrẹ awọn wọnni ti a gbala ti a si ṣe iribọmi fun. Ni Ọjọ Pẹntikọsti, nigba ti Peteru waasu ti o kún fun agbára Ọlọrun, "awọn ti o si fi ayọ̀ gbà ọ̀rọ rẹ̀ a baptisi wọn" (Iṣe Awọn Apọsteli 2:41). Filippi waasu Kristi fun iwẹfa ara Etiopia bi wọn ti n lọ li ọ̀na ninu kẹkẹ́. Nigba ti wọn si de ibi ti omi wà, iwẹfa na ri i pe anfaani ṣi silẹ fun oun lati gbọran si aṣẹ Ọlọrun ki o le ni iriri iribọmi. Iwẹfa naa wi pe, "Wò o, omi niyi; kili o dá mi duro lati baptisi?" Filippi si dahun pe, "Bi iwọ ba gbagbọ́ tọkàntọkan, a le baptisi rẹ" (Wo Ẹkọ 292). Awọn mejeeji lọ sinu omi a si ri iwẹfa naa bọmi. Lẹyin naa iwẹfa yii n ba ọ̀na rẹ lọ, o si n yọ̀.

Lidia ati awọn ara ile rẹ̀ jẹ awọn miiran ti a tun ṣe iribọmi fun. Ọkàn rẹ̀ kun fun ọpẹ si Ọlọrun fun ohun ti O ṣe fun un. Inu rẹ̀ dun nitori pe o gbọran si aṣẹ Oluwa. O fẹ ṣe ohun kan fun Oluwa. O fi ọpẹ rẹ̀ hàn nipa ṣiṣe itọju awọn eniyan Ọlọrun.

**Iṣoore**

Lidia bẹ Paulu ati Sila lati wọ̀ si ile rẹ̀ bi wọn ba kà oun si oloootọ si Ọlọrun, ati ẹni ti o yẹ si irú anfaani bẹẹ. Lidia kà a si anfaani lati ṣe itọju awọn eniyan Ọlọrun wọnyi. O ṣe e gẹgẹ bi fun Oluwa. A kà pe: "Ohunkohun ti ẹnyin ba nṣe, ẹ mã fi tọkàntọkàn ṣe e, gẹgẹ bi fun Oluwa, ki si iṣe fun enia: ki ẹ mọ̀ pe lọwọ Oluwa li ẹnyin ó gbà ère ogun: nitori ẹnyin nsin Oluwa Kristi" (Kolosse 3:23, 24). Ere wà fun awọn wọnni ti o ṣe awọn eniyan Ọlọrun loore. Nigba ti wọn ba si n gba ère naa, wọn o gbọ́ ti Kristi yoo wi pe, "Niwọn bi ẹnyin ti ṣe e fun ọkan ninu awọn arakunrin mi wọnyi ti o kere julọ ẹnyin ti ṣe e fun mi" (Matteu 25:40).

**Alafọṣẹ Kan**

Ni ọjọ kan, bi Paulu ati Sila ti n lọ si ipade adura, ọdọmọbinrin kan tẹle wọn. O ni ẹmi eṣu, o si li ẹmi afọṣẹ. O sare tọ wọn lẹyin, o si n kigbe. Eyi ṣẹlẹ fun ọjọ pupọ. Inu Paulu bajẹ nitori pe ẹmi eṣu n dá ọmọbinrin yii loro. Paulu bá ẹmi aimọ́ naa wi li orukọ Jesu Kristi, ẹmi eṣu ti o ti n dari rẹ̀ si fi i silẹ.

Ọdọmọbinrin yii jẹ́ iranṣẹ awọn eniyan kan. O n sọ asọtẹlẹ nipa ẹmi afọṣẹ, awọn oluwa rẹ̀ si n gba owo iṣẹ rẹ̀. Nigba ti a lé ẹmi eṣu yii jade kuro lara rẹ̀, ẹmi afọṣẹ fi i silẹ, awọn oluwa rẹ̀ si sọ ọ̀na ere rẹpẹtẹ wọn nù. Eyi kò dùn mọ́ wọn rara. Wọn kò kaanu fun un nigba ti ẹmi eṣu n da a loro. Ṣugbọn inu wọn bajẹ nitori pe owo ko ni wọle fun wọn lọna buburu ti o rọrùn yii mọ́.

**Ninu Tubu**

Awọn oluwa rẹ̀ mu Paulu ati Sila wọn si fa wọn lọ si ọjà nibi ti ile-ẹjọ gbe wa, wọn si fi ẹ̀sun kan wọn. Wọn wi pe, "Awọn ọkunrin wọnyi … nwọn nyọ ilu wa lẹnu jọjọ." Iyọnu ha ni lati fi opin si iṣẹ ibi nipa ṣi ṣe rere? Awawi patapata ni ẹsun wọn jasi. Nitori ikorira ti wọn ni si Paulu ati Sila, wọn rú awọn eniyan soke si awọn eniyan Ọlọrun wọnyi. Lai fi àye silẹ fun wọn lati sọ ti ẹnu wọn, wọn hu iwa ika si Paulu ati Sila, wọn fi ọgọ lù wọn, wọn si gbe wọn ju sinu tubu. A si kilọ fun onitubu ki o "pa wọn mọ́ daradara," nitori naa a fi wọn sinu tubu ti inu lọhun a si kan àba mọ wọn li ẹsẹ.

**Idasilẹ**

Li ọganjọ oru, ohun iyanu kan ṣẹlẹ. Awọn onde iyoku gbọ́ ohùn adura ati orin iyin si ogo Ọlọrun. Awọn ọkunrin meji wọnyii ti ẹ̀yin wọn n ṣẹjẹ ti a si kan ẹsẹ wọn mọ àba ha tun le yin Ọlọrun logo bi? Njẹ awọn ọkunrin meji wọnyi ti a hu iwa aitọ si yii ha tun le ni igbagbọ́ ninu Ọlọrun sibẹ? Awọn

ọkunrin meji wọnyii ti a n jẹ niya li ainidi yii ha tun le ni igbẹkẹle ninu Ọlọrun sibẹ? Dajudaju wọn ṣe bẹ ẹ, igbagbọ́ wọn ko yẹ̀, Ọlọrun si gbọ́ iyin ati adura wọn. Lojiji isẹlẹ nla sẹ̀. Ile tubu mi titi, ani titi de ipilẹ. Ide awọn onde tú. Gbogbo ilẹkun si ṣi silẹ.

**Onitubu**

Onitubu taji kuro loju oorun. Nigba ti o ri ti awọn ilẹkun ṣi silẹ, o rò pé gbogbo awọn onde ti salọ. O fẹrẹ fi ida pa ara rẹ̀. O mọ daju pe a o pa oun bi oun kò ba ri awọn ondè wọnyi mọ́, paapaa julọ, awọn ondè meji ti a fi sinu tubu ti inu lọhun. Ṣugbọn Paulu kigbe li ohun rara pé, "Máṣe pa ara rẹ lara." Nigba naa ni onitubu bere iná lati fi wo awọn ondè naa. O wọ inu tubu ti inu lọhun ti o tutù ti o si ṣokunkun dudu nibi ti Paulu ati Sila gbe wà. O mọ̀ pé eniyan Ọlọrun ni wọn i ṣe. O si mọ wi pe wọn le ran oun ẹlẹṣẹ, lọwọ pẹlu. Nigba ti o ti mu wọn jade tán, o beere pe, "Alàgba, kini ki emi ki o ṣe ki ng le là?"

**Igbala**

Paulu ati Sila sọ nipa Oluwa fun onitubu yii ati awọn ẹbi rẹ̀. Wọn gba ọ̀rọ ti wọn gbọ́ gbọ́, a si gbà wọn là. A ri wọn bọmi pẹlu lati fi hàn pe wọn ti jẹwọ igbagbọ́ ninu Jesu ati pe iṣẹ irapada ti inu ti ṣẹlẹ ni igbesi-ayé wọn.

Onitubu ṣe inu rere si awọn ọkunrin meji ti o ràn án lọwọ lati ri Jesu yii. O mu wọn lọ si ile rẹ̀. O wẹ ọgbẹ wọn, o si fun wọn ni ounjẹ. Inu rẹ̀ yoo ti dun pọ to pe oun ri igbala! Inu rẹ̀ ti dun pọ to pe awọn ẹbi rẹ̀ ri igbala! Wo bi ayọ rẹ̀ ti pọ to lati wà pẹlu awọn eniyan Ọlọrun wọnyii!

**Jijiya fun Kristi**

Lai si aniani, inu Paulu oun Sila dùn nitori pe wọn ri i pe awọn ọkàn kan ni igbala. Nina ti a na wọn kò jamọ nnkan kan, niwọn igba ti wọn ti ni anfaani lati sọrọ Jesu fun awọn eniyan. Ki ni tubu ti a gbé wọn si jamọ niwọn igba ti eyi mú ki onitubu ati awọn ẹbi rẹ̀ di atunbi? Paulu ati Sila kò ráhun nitori iya ti a fi jẹ wọn. Wọn kò sá jade lati sa lọ nigba ti wọn ri i ti awọn ilẹkun ṣi silẹ. Ohun ti o jẹ wọn lógún ni lati ṣe ifẹ Ọlọrun fun igbalà awọn ọkàn. Awọn wọnyii jẹ eniyan Ọlọrun gidi ati apẹẹrẹ rere fun wa. Njẹ a ha ni iwuwo ni ọkàn wa fun igbala awọn ẹlomiran? Njẹ a ha n yin Ọlọrun logo nigba ti a ba ni la ipọnju kọjá? Njẹ a n ṣe suuru bi, nigba ti a ba n ṣe inunibini si wa? Ọkan ninu awọn ibukun ni: "Alabukún-fun li ẹnyin, nigbati nwọn ba nkẹgan nyin, ti nwọn ba nṣe inunibini si nyin, ti nwọn ba nfi eke sọ̀rọ buburu gbogbo si nyin nitori emi. Ẹ mã yọ̀, ki ẹnyin ki ẹ si fò fun ayọ̀: nitori ère nyin pọ̀ li ọrun: bẽni nwọn sá ṣe inunibini si awọn wolĩ ti o ti mbẹ ṣaju nyin" (Matteu 5:11, 12).

**A Tú Wọn Silẹ**

Nigba ti o di owurọ ọjọ keji, awọn alaṣẹ ranṣẹ pe ki a "da awọn enia wọnni silẹ." Ṣugbọn Paulu kò kanju lati lọ. A ti doju ti wọn, a si ti hu iwa aitọ si wọn nigba ti wọn wa ni "aijẹbi." A gbe wọn sọ sinu tubu lodi si ofin, bi o tilẹ jẹ wipe ara Romu ni wọn i ṣe. A ti hu iwa aitọ si wọn ni gbangba niwaju ọpọ eniyan ṣugbọn wọn n fẹ́ tú wọn silẹ ni ikọ̀kọ. Paulu wi pe, "Ki awọn tikarawọn wá mu wa jade."

Nigba ti awọn onidajọ gbọ ọ̀rọ wọnyii, ẹ̀ru bà wọn. Wọn ti gberaga wọn si jẹ alailaanu, ṣugbọn nisisiyi Oluwa rẹ̀ wọn silẹ. Lati fi hàn pe Paulu ati Sila kò jẹbi, awọn onidajọ lọ si ile tubu, wọn si dà wọn silẹ. Wọn rọ Paulu ati Sila lati jade kuro ni ilu. Lai si aniani wọn ni idalẹbi lọkàn wọn nitori iwa aitọ ti wọn hù, wọn si n fẹ ki a jawọ kuro ninu ọ̀ran naa.

Nigba ti wọn sọ fun Paulu ati Sila lati fi ilu silẹ, ohun ti wọn n sọ ni pe ki awọn ti n waasu idande fun wọn ki o maa lọ. Ni ọ̀na bayii wọn sọ anfaani ti wọn ni lati gbọ́ Ihinrere ni akoko yii sọnu. A kò mọ̀ bi awọn eniyan tun ni anfaani miiran lati gbọ́ iwaasu Paulu tabi ki wọn tun gbọ́ nipa ti idalare mọ́.

**Pẹlu awọn Eniyan Mimọ́**

Ijiya kò ba Paulu lẹru. Oun ati Sila kò sa kuro ni ilu pẹlu ibẹru pe ki a má baa tun lu wọn. Wọn jade pẹlu ọ̀wọ̀ wọn si pinnu lati lọ si ile Lidia. Boya nibẹ, wọn sọ iriri ti wọn ni ninu tubu ati nipa igbala onitubu. Lẹyin ti wọn ti ba awọn eniyan mimọ́ sọ̀rọ ti wọn si fi ọ̀rọ itunu gba ara wọn niyanju, Paulu ati

Sila jade kuro ni Filippi lọ si ibi miiran ti o tẹle e ni ilu Makedonia nibi ti Ọlọrun n fẹ ki wọn gbe lọ waasu.

**AWỌN IBEERE**

1 Ki ni ipe ti Makedonia?

2 Ta ni ipe naa jade si?

3 Ki ni itumọ rẹ̀?

4 Bawo ni Lidia ṣe gbọ nipa igbalà?

5 Bawo ni o ṣe fi ẹmi imoore si Ọlọrun hàn?

6 Ki ni ṣe ti a fi gbe Paulu ati Sila sinu tubu?

7 Ki ni wọn ṣe li ọganjọ oru?

8 Bawo ni Ọlọrun ṣe dahun adura wọn?

9 Ki ni o ṣẹlẹ si onitubu?

10 Ki ni Paulu ati Sila ṣe lẹyin ti a da wọn silẹ kuro ninu tubu?